CHANGE of NAME
I formerly known and called Miss M. I. DADA of the Ansar-Ud-Deen School Ilisan Remo, wish to be known and called Mrs. M. I. SOLARIN as from 21st March 1958
Ducuments bearing my former name remain valid.

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

READY FOR SALE
Iwe Arofọ ti -:
ANỌYIN LOHUN-BI-ỌMỌGE IMARO
APA KETA
LATI OWỌ
G. A. SOWUNMI
Price 2/-
Modupe Press
16, Bamgbose Street,
Postage Extra

VOL. I No. 49 WEDNESDAY JUNE 4, — JUNE 10 1958 KỌBỌ KAN

## OKO ELERO DANU

## ENIA MOKANDINLOGUN BA OMI LO

EKO

GBOGBO AWỌN ỌKỌ ONIGI TI NWỌN BA GBE ẸRỌ OYINBO SI LATI MA FI TU ỌKỌ NA NI AWỌN ARA EKO NPE NI YASAIDI.

IRU ọkọ yi kan ko wọn ero, a gbọ pe nwọn fere to ọgbọn enia, lati Eko lọ si Apapa. Bi ọkọ na ti ṣi, agbo pe ko tete sare pupọ, ṣugbọn nigbati o de oju iṣan ti iṣan le, lo ba fi ere si larin agbami rere

BOYA atukọ na ko tete ri oye pe iṣan odo ọsa le gbe ọkọ na lọ kọlu awọn laita ti o mbẹ ni waju ni, lo ba tunbọ gba ina mọ ọkọ na, de'ipo ti ko ṣe daduro mọ titi o lọ fi ori sọ ọkọ laita ni arin agbami-jigbun nitosi ibiti jamba kan ti ṣẹlẹ laipẹ yi.

NṢENI gbogbo awọn awọn enia danu sinu omi A si gbọ wipe lọgan, awọn ọlọpa ti gbe ọkọ soju omi enia diẹ ni nwọn ri gbala, awọn enia yoku bi mọkandilogun ti ba omi lọ.

Diẹ ninu orukọ awọn enia ti o moribọ ninu ewu na niwọnyi:- Florence Misia, Marina Bush Apapu, Tijani Elesha Oriyọmi, 59, Idunṣagbe St, Lagos, Sylvester Amako, Nigerian Brewery Apapa, Johnson Ogungbọla, 6, Ẹlẹgbata St. Lagos, ọkunrin yi ni Dereba ọkọ na. Samuel Fadayibi 7, Cole Street Lagos.

ADURA. A mbẹ ọ Ọlọrun, lọwọ iku omi, iku gbigbona, ati iku ojiji, Oluwa rere gba wa o.
Amin, Amin Amin.

awọn igbimọ titun joko lati yan baba isalẹ ati Alaga.

Ninu ipade yi gbogbo igbimọ ti wọn ni jẹ, mẹrindinladọta okanlelogoji jẹ ọpẹ, meta jẹ enia ti ko fara mọ ẹgbẹ kọkan, awọn ojoye meji. Gbogbo wọn panu pọ lati ni Ọba Alayeluwa Fẹsọgboye II Ọba Agbọwa gẹgẹ bi baba isalẹ.

NIGBATI wọn fẹ yan alaga awọn igbimọ mọ-

(Wo oju ewe kẹrin)

## Agbowa - Ikosi yan Igbimo Tuntun

AGBỌWA-IKOSI

Ni ọjọ kerinlelogun oṣu karun ti nṣe ọjọ Satide ni

No. 76

## PUBLIC NOTICE

### IS YOUR RADIO LICENSED ? ? ?

In order to remove any misunderstanding that is likely to arise, it is necessary to inform all owners of wireless receiving sets that it is an offence under the Wireless Telegraphy Ordinance (Cap. 233) and the Regulations made thereunder for any person to use a radio unless he is in possession of a current Broadcast Listener's Licence.
Regulation 15 of the Wireless Telegraphy Regulations states as follows:

"13 (1) The following fees shall be payable for each year or portion thereof during which any licence is in force, but licences issued on or after the first day of July in any year shall be chargeable with only half these rates:—

(d) For a broadcast listener's licence.-
Class A —

| | | |
|---|---|---|
| (i) | Private residence ... | 10s. |
| (ii) | Cafes, restaurants, hotels and clubs | £5. |
| (iii) | Public entertainments; e.g. public halls, bioscopes, etc., open to the public on payment of a charge ... | £20 |
| (iv) | For other premises or in special circumstances such fees as the Director of Post & Telegraphs may prescribe ......... | |

The fee for a Broadcast Listener's Licence is 10/-d. The Licences expire on the 31st day of December of each year and are renewable at any Post Office.

## ONIWE IROHIN LO BE ILU GESI WO



Nihin ni Ọgbẹni Raphael Ademọla Olotu iwe Irohin "Siera Leone Observe" ṣe igbinyanju lati wa ọkọ ti a fi ntun ọkọ ṣe. Awọn ti wọn si nwo ni (lati ọwọ osi) Ọgbẹni Addin Boyo, igbakeji ọga Olotu iwe Irohin "Daily Service" ti Naijiria, Ọgbẹni Ayọ Adefọlaji igbakeji ọga Olotu iwe Irohin "West African Pilot" ti Naijiria, Ọgbẹni Emanuel Jaja Olotu iwe Irohin 'Daily Times' ti Naijiria, Ọgbẹni T. W. Archer ati Ọgbẹni J. E. Whitelegg "Colonial Office" ni ilu Oyinbo ẹniti o nṣe ibojuto irin ajo na ni ile iṣẹ Irohin ni ilu Oyinbo.

# IMOLE

ẸBIN ỌRỌ WA:- IMOLẸ DE OKUNKUN PARADA

*EDITORIAL WORKS & OFFICE*
**16, Bamgbose Street, Lagos**
**Telephone:- 21985**

*London Office:-*
*Sunday Ayorinde:- 5, Hemming Street London E. 1.*

UNITED KINGDOM REPRESENTATIVE
PUBLISHING DISTRIBUTING CO. LTD. MITRE HOUSE
177, Regent Street, London W. 1.

FUN OWO "IROHIN IMỌLẸ" ỌDUN KAN
EKO— Ṣile Mẹrin ati Kọbọ Mẹrin (4/4d)
Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun, Sile Mẹfa ati Kọbọ Mẹfa (6/6d)

## Enito jin si Koto ko ara iyoku L'ogbon

ITỌKASI pataki ni ọrọ akọle wa ti ọsẹ yi jẹ fun gbogbo ẹnyin ọkawe wa paapa ẹnyin Ọdọmọkunrin asiko yi ti o jẹ wipe ẹ ko mọ ohun meji lẹhin ki ẹ yi iwe pada nibi tabi nida keji ẹnyin ti wọn fi ṣe asoju ni Bode ẹru (Customs) ti ẹ ko ni ero meji ju pe ki ẹ ko ẹru-ẹlẹru ti awọn fi yin sọ. Pẹlẹpẹlẹ ma dọwọ nyin Ẹnito jin si koto kọ ẹnyin ara ti o ku ti awo yin ko ti lu l'ogbon, nitoripe ti awo yin ba lu ẹniti ẹ ti ni iyi lọdọ ẹo wa di ẹni yẹpẹrẹ orukọ nyin papa yio si wa bajẹ loju gbogbo enia nigbati ọwọ awọn Ọtẹlẹmuyẹn ọdaran.

AWỌN agba lo ma sọ bayi pe Ẹnito ba mọ aiye jẹ ki gun ọpẹ. Ti ẹ ba ka iwe Irohin ojojumọ ti ọsẹ to kọja ẹ o ri wipe ẹjọ awọn ọdọmọkunrin nwọn ko ẹru-ẹlẹru ni Bode ẹru (Customs) ni o poju nwọn si ti gba idajọ wọn ẹkun rẹrẹ.

ỌPỌLỌPỌ aboṣi ti mbẹ laiye lode oni ti iba jẹ ẹni-nla ati ọlọla laiye wọn, nwọn ti fi wadu-wadu ati ikanju jaiye wọn, nwọn si ti lọ ṣ'ẹwọn ọdun gbọrọ BI o ba ṣe pe wọn tete gbọ ohun ti awọn agbalagba tabi nwọn tẹle ọrọ inu iwe irohin ojojumọ tabi ti ni dajudaju koni b::ru bayi fun ẹnyin akanju jaiye ọdọ, ṣugbọ nawọn elomiran mbẹ bi o kọ wọn titi wọn ko ni gba eti wọn ti di bi eti ikun, Igbẹhin-gbẹhin ti awo wọn ba lu tan ti ọwọ awọn ọtẹlẹmuyẹn ba tẹ wọn nigbana ni yio wa ye wọn.

ENITO JIN SI KOTO KỌ ARA IYOKU L'ỌGBỌN

AWON IWE KOSEMANI TI O WA NILE FUN TITA NISISIYI

| | |
|---|---|
| Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan | 2/6d |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan pẹlu Itumọ Ala | 20/- |
| Itan Aladun Iede Yoruba | 3/- |
| Ajiran Ilu Oku | 3/- |
| Waka Bisiriyu Apalara | 1/- |
| Itumọ Ala ati Itumọ Ami ʻra | 3/- |
| Iwe Owe Yoruba | 3/- |
| Psalm Iṣẹgun Ajẹ ati Aiye pẹlu Turari | 17/6d |
| Turari Itaja, Ẹyọnu Ajẹ ati Adura | 10/6d |

Fi owo ọja rẹ ati 1/- ranṣẹ si :-
Fi owo ati Stamp 1/- ranṣẹ fun gbigbe ọja rẹ pada
J.O. SHOYINKA c/o Post Office Ebute Mẹtta
Tabi
8, Ojo Road (Oduabọrẹ) Mushin.

AWỌN IWE TI A ṢESẸ FẸ TẸ JADE
Igbo Esubeleke (kikun) 4/6d, Irin Ajo Ajanpako (kikun). 4/6d Ayunọrunbọ ati Panpalaṣo 4/6d, Ajiran Ilu Oku (kikun) 4/6, Sebotimọ Ọrẹ mi 3/-, Mafaro Ṣere 3/-, Igba ko lọ bi Orere 3/-
Akiyesi :- Ẹ o ma gbọ nigbati o ba jade

# Iwe Si Olotu

## Ilu Omupo Nfe Iranlowo IJOBA

OLOTU jọwọ gbami laiye lati dahun si ọrọ Ọgbẹni Majẹkọbajẹ Omupo ti o jade ninu iwe ti ọjọ kọkanlelogun oṣu karun ọdun yi 21/5/58 eyiti o jẹ ọrọ ẹdun fun emi papa, gbogbo ipo ti o ba yẹ ki a wa, ki a jẹ ẹnikan ti o nsọrọ ni ilu, o yẹ ki a le ṣe aṣaro nipa ọrọ ile iwosan ninu akọkọ eto yin, bi ẹ ba sọ ti wọn ko gba, ẹ tun tẹnumọ ọrọ kanna, ki ẹ si tun wa ṣe aṣaro nipa ti Post Office. Ohun mejeji wa jẹ ohun ti o ṣe pataki ju ni arin ilu.

Ara ile ni ogun ọrọ Igbe orukọ ga ni Post-Office jẹ, ifitẹlẹ si ni ile iwosan jẹ, Post Offie si jẹ igbekalẹ, Ọja si wa ni o jẹ bi ipokẹta. Ki a ma panumọ ki a tẹnumọ ohun ti o ndun wa yi ki wọn fun wa.

A bẹ awọn Ijọba Ilọrin pupọ ju ki wọn ṣe fun wa ni ohun ti a tẹnumọ yi. nitoripe awa ko si ninu awọn ti o ma nfi owo-ori jafara rara. Lẹhinna ki ẹ ba wa ṣe aṣaro lori rẹ, ki a si ma ke pe Ijọba ninu iwe Irohin ni gbogbo igba fun ẹbẹ ilọsiwaju ilu wa.

Mo dupẹ aye ti Olotu gba mi.

Emi ni
Y. A. G. Lawal

OLOTU jọwọ gbami laye lati tẹ iwe yi jade.

Awọn agba npowe kan pe, Ti ina ko ba tan ni aṣọ ẹjẹ ki tan ni ekanna. Mo ki awọn oṣiṣẹ ale pupọ fun iṣẹ wọn na, nitoripe wọn ti npari iṣẹ wọn titi agogo mọkanla, ko si tun si wipe awọn onile tun nti ilẹkun, ti awọn oṣiṣẹ yio si tun ma kakun ki wọn to ṣiṣẹ. Mọto ti awọn L.-T.C ko sita ti a fi nṣe iṣẹ na dara pupọ, nitori ti ẹ ba de Idunmọta ni nkan bi agogo mẹjọ alẹ, nwọn yio ri wipe o dabi moto tank epo Petrol, kosi ẹniti o le mọ wipe igbẹ lo wa ninu rẹ

Mo si tun ki awọn L.T.-C. fun inawo wọn lori irinṣẹ ti wọn ra lati fi ṣe iṣẹ na. Mo si tun ki awọn oṣiṣẹ alẹ na pupọju, Baba mi npa owe pe Omi ki kun bori ẹja. Gbogbo owo ti awọn oṣiṣẹ na ba si gba nibi iṣẹ wọn yio ṣe nwọn ni anfani. Mo si tun ki awọn olubẹwo na, ọkọ Ijọba ko ni ṣa yin lẹsẹ, amin iwaju lao ma lọ o, ki Oluwa ki o pẹlu gbogbo wao.

Emi ni
David Boy Ige
O ṣe ọmọ Ahinkẹ ṣe ọmọ
SABA

## Ifi imosokan ati ifi owosowopo ni a le fi mu Ilosiwaju wa si ilu wa

NINU ipade pataki kan ti awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ N.C.N.C. ṣe ni ilu Majidun ni ọsẹ to kọja Ọgbẹni E. A. Aworetan ti nṣe Alaga ẹgbẹ N.C.N.C. Majidun Owutu Branch sọ ninu ipade na pe nipa ifi imọṣọkan ati ifi imọṣọwọpọ ni a le fi mu ilọsiwaju wa si ilu wa sọ eyi lati dupẹ lọwọ awọn aladugbo rẹ fun akoko idibo Ikorodu Local Council eyi ti wọn ṣe ni ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu kẹrin ọdun (26April 1958) Ọgbẹni Aworetan tun kanṣara si gbogbo ilu Ikorodu ati agbegbe rẹ fun iru ifẹ ti wọn ni si awọn aṣoju ti ẹgbẹ Alakukọ yan si ita kakiri ilu Ikorodu, eyi ti gbogbo ijoko rẹ jẹ Mọkanlelọgbọn (31) ti ẹgbẹ Alakukọ (N.C.N.C.) ni ijoko Mejidinlogun (18) ti ẹgbẹ Ọlọpẹ (Action Group) ni ijoko mẹtala (13) ni ilọsiwaju ninu ọrọ rẹ, o ni

ki gbogbo nyin fi imọṣọkan ati ifi ọwọṣọwọpọ pẹlu awọn aṣoju yin ni gbogbo nkan le fi lọ dede, o

(Wo oju ewe kẹta)

